# ELETI OFE

'A-NJU-WON KO SE WI LEJO'

VLO XIV NO 894 LAGOS SATURDAY NOV. 9— NOVEMBER 15 1963 KOBO MEJI (2D)

### Ilu Onitsha 'Tu Faga' Nitori Enia Kika

# Awon Onisowo Ibo Gb'oko Won Lo

ONITSHA — Nitotọ ni owe ti awọn Yoruba pa wipe ọmọ ale ni fọwọ osi juwe ile baba rẹ; irohin apapọ ti a ri gba lati ọwọ akọwe onirohin wa ni Ipinlẹ Ila Orun lori gbogbo awọn enia ti nwọn tun ka kakiri ilẹ Nigeria ni o jẹki a pa iru owe bayi. A gbọ wipe lọjọ ti nwọn fẹ bẹrẹ enia-kika na nilu Onitsha nṣe ni ọja Onitsha 'tı faga'' ti nwọn ko si ri ẹiyẹ ki o wa patẹ lọja na.

Akọwe onirohin wa fi ye wa wipe nigbati awọn ọmọ Onitsha onilẹ yio fi fura si nkan na, gbogbo awọn ajoji Ibo ti o ngbe ibẹ ti nfi ilu silẹ lọ si igberiko ti nwọn fi ori olukuluku sọlẹ si ki awon akọwe ti nka wọn le ba ri wọn ka loko wọn.

A gbọ wipe owurọ Ọjọ 'Ru tiṣe ọjọ keji ti nwọn bẹrẹ enia kika ni o le pupọ ju. Gbogbo mọto-akero ni nwọn bẹrẹsi ko ero kuro nilu bi ẹni wipe nkan buruku kan ni o nle wọn lọ tọmọ-tọmọ.

Nigbati awọn akọwe akania paapa ko ri ẹnikan ka bi alara ni awọn na ba fura, ti nwọn kigbe ọrọ na lọ ba ọga wọn, Ọgbẹni N C Perkins, on paapa lọ sọ fun awọn ọlọpa wipe ki nwọn ran awọn lọwọ lati lọ ma da mọto wọn pada loju ọna toru toru.

Gbogbo bi awọn Ibo kan ti nṣe nṣe wahala tọsan toru wipe nwọn ni lati ka awọn tọmọ tọmọ ni awọn ni igberiko ka ni Nsuka leti Enugu, awọn Ibo Igbo Etiti faake kọri

(Wo iyoku loju ewe kẹjọ)

## Awon Egbe Onisegun Sile Iwosan Si Itafaji

EKO-Lẹhin igbati ilẹ Nigeria ti gba ominira ni agbatan orişirişi nkan anfani ni a ti nri nilu, ọkan ninu wọn ni ILE-IWOSAN tuntun kan ti gbogbo awọn ẹgbẹ onişegun ibilẹ enia dudu ti orukọ ẹgbẹ wọn njẹ Nigerian Association of Medical Herbalists, şi si namba mẹta ni Opopo Willoughby ni Itafaji l'Eko laipẹ yi.

Akọwe onirohin wa ni nigbati on de ile iwosan ibilẹ awọn onişegun na ni owurọ ana nkan, orişirişi ti o ba oju mu lọna ti nwọn fi ngba wo arun ni on ri pelu awọn aboyun ati awọn obinrin ti nwọn nwa ọmọ ti nwọn wa gbogun.

Dokita Z O Salimon pẹlu awọn oluranlọwọ rẹ; awọn bi Ọgbẹni L A Adeshẹgun, "Ọba bi Ọlọrun ko si" ati awọn nọọsi obinrin ti nwọn mba wọn şişẹ nile iwosan na bẹrẹsi fi gbogbo nkan han mi leto-leto bi awọn ti nşe işẹ.

Wo yoku loju ewe kẹjọ

## Baba Alabiku Ni Ki Won Ma Ka Omo On

AGEGE—Ijangbọn ti ọrọ enia-kika da silẹ larin awọn Yoruba ti ko mọ nkan bi aiye ti nlọ si ko nşe nkan kekere paapa laroko kakiri. Baba''alabiku ọmọ kan lọ okun-tayı (tie) mọ akọwe akania lọrun lọjọ ti nwọn nka enia ni agbo ile kan ni 96, Oju-Opopo Ararọmi ni Oshodı leti Eko nibi., O ni ko gbọdọ ka awọn ọmọ on rara nitoripe eyiti nwọn wa ka nijọsi ti da on nile ru patapata.

Baba Alabiku na ni ki akọwe akania, Ọgbẹni Akinlaja yara şi ''iwe-esu'' benbe ti o le mọ oju ọna abawọle on, bibẹkọ akọwe na ko ni lọ. O ni lọjọ ti nwọn ti wa ka awọn ọmọ on ni nwọn ti nku ni tẹlentẹle, o ni awọn ti ko ti ku wa ninu amodi ti awọn nwo wọn loju ninu ile nisis yi A wi eleyi tun gbe iwe-alusi wa ba on,

Nibiti nwọn gbe nfa ọrọ na lọwọ ni ọkan ninu iyawo baba na de lati ọja o ni a fi bi akania na ba şi iwe-lenbe ti o lẹ mọ ẹnu ọna awọn bibẹkọ ko ni lọ, lọpẹlọpẹ awọn aladugbo ti o gba a lọwọ tẹ.

(Wo yoku loju ewe kẹjọ)

## LAGOS RACE CLUB

The LAST DAY October Race Meeting will take place on Saturday 9th November, 1963.

First Race at 3.30 p m.

Sweepstake will be drawn on the numbers of Admission Tickets. 1st will be paid £2 10/-, 2nd £1 10/- and 3rd 10/-.

Also Two Silver Cups will be presented to the best dressed Ladies in national costume and Western dress.

COME ONE COME ALL

Hon. Secretary
LAGOS RACE CLUB

# New London Air Terminal Opened

LONDON—The new West London Air Terminal built to deal with 6-7,000,000 passengers a year, was opened yesterday, Wednesday, by the Duke of Edinburgh.

It is anticipated that in the coming year more than 3,000,000 passengers-travelling by British European Airways and the twenty-four airlines for which B.E.A. act as agents will pass through the Terminal which cost £5million

The biggest and most modern of its kind in the world, West London terminal is ten storeys high covers an area of 4 acres, and is built on stilts over the London Transport's Underground junction at Gloucester Road.

Facilities provided include automatically controlled heating of ramped vehicle roadways to avoid freezing, nine passenger and two goods lifts, automatic opening and closing of doors for passenger operated by a concealed floor switch, and two converyor systems handling 2,000 pieces of luggage an hour.

By the end of next year, as a result of neigbouring road and tunnel improvements, the joining time from terminal to airport will be reduced to thirty minutes.

## Nigeria Orders 305 Truck Chassis From Britain

LONDON—Over three-hundred diesel-engined truck chassis from Britain's Leyland Motors and its Glasgow associate, Albion Motors many of them for use in agriculture and contracting work in development projects, have been ordered for Nigeria by the British West Africa Corporation Limited, Birmingham which earlier this year ordered 130 Leyland and Albion Trucks and buses.

A spokesman for the British West Africa Corporation told one of our correspondents no Wednesday, that the order was to fill general stoks. The vehicles would be shipped out to Nigeria in chassis and cab form and bodies would be assembled in Nigeria to fit special demands,

The contract signed with the Leylands Group is the largest single order received by the Group from Nigeria in recent years; Deliveries of the vehicles will begin about May next year and continue into August. They will be sold through the British West Africa Corporation agencis in Apapa Enugu Kaduna, Kano, Jos, Port-Harcourt and Ibadan.

The latest contract covers 175 Leyland Comt haulage and tipper models with 125 h.p. diesels engenies; 100 Albion Chieftain Super Six haulage models with 125 h.p diesels; and 30 Albion Super three-axled haulage models with 125 h.p. diesel engines.

## Awon Olopa Ibile Ibadan Ko Rowo Osu Gba

IBADAN—Dẹ kọ ni ariwo ti awọn ọlọpa Ijọba ibilẹ pa si awọn ọga wọn leti ni Bareke Agodi nigbati awọn de ile iṣẹ aṣẹ awo, ti awọn ni ko si owo nilẹ ti awọn yio fi san owo-oṣu fun wọn.

Gbogbo awọn obinrin ti nwọn ti taja awin fun wọn lati ibẹrẹ oṣu ni awọn faake kọri wiję awọn ni lati ba wọn de ile iṣẹ wọn nitoripe ọrọ na dabi iro loju awọn.

Ọkan ni u awọn obinrin na Kalẹ.u Oke Bẹrẹ ni awọn marun ni on ta awin aṣọ fun ninu iyawo awọn ọlọpa na, epinni on ko si ti ri gba bẹ on si ni lati san owo fun Oyinbo Kọra ti o gba on lawin aṣọ.

Akọwe onirohin wa ni ọga awọn ọlọpa na, Ọgbẹni J. A, Oloyede ni awọn marundinlogerin ni o ku ki awọn san owo oṣu fun ninu gbogbo awọn ọlọpa ibilẹ mẹtadinlọgọrun ti nwọn nṣiṣẹ fun awọn nile ati Iroko.

# Oko Itoju Adie



Gbogbo Ijọba ngbaiye ni nwọn ti nkegbe lemọ lemọ wipe ki olukuluku awọn alamojuto Ijọba ilu kọkan mura si ọna ti onjẹ yio ṣe pọ ni aiye nitoripe enia npọ si laiye.

Eyi ni o jẹki olukuluku wọn ran enia lọ si ilu Oyinbo lati ma lọ kọ iṣẹ bi nwọn ti nsin adie. Aworan yi ni ti ọkan ninu awọn akọwe ti Ijọba ilu kan ron lọ si ilu Oyinbo fun ẹkọ lori sinsin adie. m'rsn ni ilẹ

Ni Agege, Ibadan oto Enugu, Zaria ati ibofi Nigeria ni Ijọba ni oko adie sinsin si,

# Alcoholism – An Ill-ness

## (By a BBC Correspondent)

The most widespre d addiction today was notto drugs such as cocaine or heroin, but to a cohol, said consul ant psychiatrist Dr P.H. Connell in a recent broadcast to the BBC General Overseas Service weekly programme 'Science and Industry'. The difference between a heavy drinker and an alcoholic was that the former might, for social reasons, drink a great deal at weekends, while the alcoholic had become depent no drink, and eventually could not do without it.

Dr. Connell maintained that while no one was born an alcoholic, some people were born with certain personality potentialities, which without a specifically helpful npbringing might eventually result in a proneness towards alcoholism. Someone basically insecure someone unable to face up to stresses who didn't mix well, might, without the artificial courage of alcoho, feel inadequate and inferior.

Previously alcohol was thought to be a stimulant; more recently it had become known to be a depressant. Today the actual area of the brain that alcohol depressed, with a resulting disintegration of judgment and the memory, had been discoveed to be the Reticula Formula.

Because of many different types of personality involved, the actual treatment of an alcoholic could be difficult. But Dr. Connell maintained that an alcoholic was a person who certainly needed treatment, because he was, in fact, a sick man. With treatment, he thought that about a third of the alcoholic would recover a third would be much improved and again roughly a third would not benefit from out-patient treatment and would need to be in-patients in an institution.

There were a number of types of medical treatment for alcoholisim which depend on a petient feeling very sick if he took a drink after certain drugs had been absorbed into his blood-steam. Subsequently it would be hoped that he would associate feeling ill with drinking. After a priod of abstnsion however, he might be tempted to think that one little drink wouldn't do him any harm., But alcohotics could not restrict themeselves to one little drink.

It was specific medical treatment that social factors became extermely and increasinlgy important, Dr. Connel said After all, a a person whom alc hol had helped to overcome his personality problems could not return to society without some compensation for the "Dutch courage" previously provided for him by drink. It was at this stage that organisations like Alcoholics Anonymous were necessary, or social clubs which would usefully help to fill in the time previously spent by the alcoholic propping up the bar.

Dr. Connell felt, though, that there was no really clerir-cut solution yet to the problem of alcoholism. There must, he felt be a long-term attack on it, and prevention in terms of family care and child psychiatric units should play an increasingly big part in this attack. At the the same time, Dr. Connel thought that so long as there were no excessive cultural sanctions against alchol, there would always be alcoholics. The job was to cut down the numbers.

## Mbu Peregede Ni Ipade Agbaiye

ACCRA—Ọgbeni M T Mbu, minisita alamojuto eto awọn ọmọ ogun oju omi ṣe bebẹ nibi ipade igbimọ abo labẹ ominira ti gbogbo awọn ilu Afirika ti nwọn gba ominira ṣe lọsẹ ti o kọja.

Ọgbẹni Mbu ni awọn ti ṣe ipinnu lati fi ilu Addis Ababa ṣe ibi ijoko ile iṣẹ awọn ọmọ ologun na igbimọ na ni yio si ma wa alafia fun gbogbo orilẹ afirika lasi ipalara rara.



Mr. M T Mbu

(Wo iyoku ni ewe kẹrin)



# ELETI-OFE

( ANJU WON KOSE WILEJO )

EDITORIL OFFICE & WORKS CBLE & TELEGRME
28, Kosoko Street, Lagos. "ELETI-OFE" LAGOS
P. O. Box 467 Phone 23370

VOL XIV. NO 824 STURDY NOV. 9 - NOV 15, 1963


Oro Olotu:

## Rogbodi-yan Yi To

Awon Yoruba ni ngbalagba ti o nsare ninu okan kise lasan, bi ko ba le okan a je wipe nkan nle e. Oro rogbodiyan ija ti o nfi ojojumo besile logba awon elewon Ilesha yi ni o jeki a pa owe nla yi.

Laipe yi ni a gbo irohin wipe elewon na faake kori ti nwon lu ara won ati awon dereba won ni alubolo ti okan ninu won ku bamubamu, ti awon miran si npoka iku nile Oniwosan.

Ki a tun ji ni ijeta ni a tun gburo wipe awon elewon ti nwon tun ko lo si Ilesha na ti tun nlu awon oga won ni kunmo alubole.

Awa onirohin Eleti-Ofe ri wipe eyi nu a je eko fun Ijoba wa nwon yio si tete se iwadi nkan ti o nbi awon elewon na ninu ti nwon fi nfi ojojumo faake ko i. Abo oro ni a so fomoluwabi.

## Ikomojade Ogbeni Elliott Dun

IBADAN—Ni ojo Abameta ojo keji osu yi ni Ogben Akin Elliott, akowe agba ile ise awon Nkan Ogbin (Ministry of Agriculture) se aseye ikomojade omo tuntun ti iyawo re Bolaji sese bi fun un ni Oko Ado. Nwon si so oruko omobinrin na ni Olufunmilayo, Modupe, Oluwatoyin, Mojisola Sakanni Animaun

Ogunlogo awon ore ati ebi lati Eko pelu Ibadan ni nwon pese sibi aseye ikomojade na. Ogbeni Tunde West Nightingale ni o fi ilu Juju re da awon ti o wa nibe lara ya lati asale titi tile fi mo ti gbogbo awon enia si nbi iya abiyamo na jo lukuluke.

Gbogbo awon enia jankan-jankan lokunrin ati lobinrin ti nwon wa sibi ikomo na ni baba omo na fi okan jije ati mimu te lorun. Die ninu awon enia pataki ti o wa sibi aseye ikomojade na ti a le daruko niyi, awon bi Dokita Ayorinde ati aya re, Ogbeni A.B.A Johnston ati aya re Mosin, Ogbeni Remi Macauly, Oged Macauly, Akanbi Callisto, S M Okuwobi, Olu Hamilton, Sholanke, Eboda, Oyelade, Amole, M.A Ogunyemi, G. Thompson;

Iya-afin Elsie Macauly, Hanson, Tayo Macaulay Ogedengbe, Layide Oduns, Tanimowo Ode, Ogunsanya Mabel Efunshile pelu awon iyawo alarede awon Ogbeni ti a daruko si oke iwe yi.

"Elly Republic" Oluwa ki o da o si.

# Iwe Si Olotu

## Mbu Peregede Ni Ipade agbaiye

( O bere loju ewe keta)

Ijoba ilu Dahomi nikan ni ko le iran iko wa nitori rogbodiyan ti o be sile ninu won laipe yi. Ogbeni Mbu ni awon ko fenu kan oro rogbodiyan won na rara ni ipade na.

Ogbeni Mbu ni awon ara ilu Congo ni won mu esun awon ara ilu Portugal wa si ipade na ki awon to tuka.

## E ka Iwe Irohin ELETI-OFE losose

## Bolu Afesegba



(Awon elere bolu afesegba, Arsenal pelu West Ham yio fi aga gbaga ni osan oni ni London boya oni ni nwon yio sere won na nitoripe awon mejeji to ara won.

# Nihin Lohun Ati Nibi Gbogbo

## Lati Owo Ayiluka Enia-Kika

Eto enia-kika ti o tẹ yi yatọ pupọ, emi Ayiluka gbadun rẹ ṣugbọn nkan ni o fẹrẹ ba ehin aja jẹ, iyen ni ti awọn ẹmọge ti nwọn ran lọ kania ni Oke Ọya ti atẹgun ibẹ ko mọ wọn lara. Mo gbọ wipe ọpọlọpọ wọn ni nwọn bẹrẹsi sin, ti nwọn nyan lodilodi ni gbara ti awọn ti gunlẹ.

### Omi Sokoto

Omi ilu Sokoto yatọ si ẹmu Mbawsi ni Aba ati Odo Imo, bẹ si ni Shinkafa Hausa yatọ si Apu ilu Ibo; gbogbo iyatọ yi na ni o fẹ ko wahala ba awọn ọmọge wa ti a ni ki nwọn lọ foju kan awọn ẸLẸHA NINU IYARA wọn l'Oke Ọya.

### Awon Eleha

Mo gbọ wipe atẹgun ati omi pẹlu onjẹ nikan kọ lo di awọn ọmọge wa lọwọ ọna ileto kan si ekeji ti o jin si ara wọn, ti nwọn ni lati gun kẹtẹkẹtẹ, rakunmi ati ẹṣin jọki arẹ ba awọn ọmọge wa nitoripe a ti fi mọto ayọkẹlẹ ba wọn jẹ ni isalẹ Odo Ọya.

### Ara Eko

Ko si ẹniti o sọrọ ka bi awọn ara Eko, awọn ti nwọn nsun nita fẹrẹ pọ ju awọn ti nwọn nsun lọdẹdẹ lọ. Awọn ti nwọn nji lọ si oko-aru wọn ni agogo mẹta ọganjọ oru ni o fẹ ka ni tabi awọn obinrin alaṣọ l'Ereko ti nwọn ko ofoju kan ọkọ wọn lọsan afi loru. Mo gbọ wipe awọn akọwe akania ka gbogbo awọn enia ti o nsun ni oja Jankara ati awọn iyawo wọn patapata.

### Awon Elewon

Mo gbọ wipe awọn ti o wa lọgba ẹwọn paapa kọwe si Ijọba wipe awọn fẹ ki nwọn ran akọwe wa ka awọn na nitoripe enia ni awọn na ọtẹ lo tẹ awọn ti awọn fi de ọgba. Nitotọ o yẹ ki nwọn lọ fi awọn ẹlẹwọn ti nwọn wa ni opopo Broad Street, Ikoyi, Kirikiri, Agodi ni Ibadan, ni Oke Igbein l'Abẹokuta ati awọn ẹlẹwọn onijangbọn Ilesha, awọn ẹlẹwọn janduku ti Kakuri ni Kaduna pẹlu awọn arufin Ẹnugu.

### Omo Elliott

Ọpọlọpọ awọn ọrẹ mi atijọ ti mo ti fojukan ti pọ ni mo ri ni ibi ibikomọ Ọgbẹni Akin Elliott, akọwe agba ibiṣẹ nkan ọgbin (Ministry of Agriculture) ni Ibadan, ti iyawo rẹ Bọlaji ṣẹṣẹ bi fun ni adugbo Imalefalafia ti nwọn ngbe. Eto ikomọ na kamama. Orukọ ti awọn sọ ọmọ tuntun to mejọ—die ti ma da ninu orukọ ọmọ na ni OLUFUNMILAYỌ, MODUPẸ, OLUWATOYIN, SAKANNI ANIMAUN, MOJISOLA ELLY REPUBLIC,

Baba ọmọ na na owo pupọ fun gbogbo awọn ti o wa si ibi ikomọ na.

Ọmọ tuntun na ti di ara wa, on si wa ninu awọn ti nwọn ka ni Ibadan lọsẹ yi. Ọlọrun Ọba ki o da ọmọ na si, ki o si lọwọ lẹhin.

### Alagbara

Mo gbọ wipe Ọgbẹni R.A. Fani-Kayọde (ẹ fori jin mi o ti di Oloye Olegboni ni Abẹokuta nisisiyi) ni ki awọn ẹmọlẹhin on ye pe en ni ALAGBARA mọ nitoripe Ọlọrun ni alagbara. Iyen wun mi pupọ ṣugbọn awọn janduku ti nwọn ri n-an gba lọwọ awọn oṣelu fẹran lati ma fun wọn lorukọ ti baba ko fun wọn, ẹnu ẹni ni a fi nkọ orukọ buruku.

Agbako Ori Ẹdẹ!

# Oko Iyawo Ku Lojo Igbeyawo

ILESHA — Agbako ori ẹdẹ, a ko gbọ iru eyi ri si igbe ti awọn ... nigbati awọn gbọ wipe ... ti orukọ rẹ njẹ Adedeji Ogunmola ... ninu ... gbe ti nwọn ...

Nkan ti a gbọ nipa Ọgbẹni na ni wipe ... o ku yi ni o ṣẹṣẹ gbe iyawo tuntun kan, ... pada dele, o ... kan ti o gba baluwẹ lọ, o ni ki on tete lọ ... awọn to gbe iyawo ... de.

O wa ni baluwẹ titi, ... wakati kan ... ninu ọmọ rẹ to fura si ... kan ilẹkun titi ko ... ki baba rẹ na ... a lohun. Ọmọ na si ... fun awọn ... nigbati awọn agbalagba si ilẹkun baluwẹ oku Adedeji ni nwọn ri pẹlu ... lọwọ rẹ.

Bi awọn ti ngbe oku Ọgbẹni ni jade ni baluwẹ ni iyawo ... ti o ṣẹṣẹ ... de pẹlu awọn ẹrẹ rẹ.

Alagbara Kan Niyi



Ṣe iwọ le ṣe bẹyi ? ki o fi ehin rẹ gbe irin nla kan nilẹ ? Ọgbẹni alagbara yi ko kọ nkan ti o le da silẹ o fi ehin gbe ina.



# Nigerian Becomes British School Head Boy

Nineteen year old Peter Thomas from Lagos in Nigeria, son of Nigerian judge, has been appointed Head Boy of Taunton School, a leading English public School established 115 years ago, and makes history by becoming the first boy from outside Britain to hold this prized school post.

Peter is seen with prefects and other pupils between classes at Taunton School, where besides doing well in the classroom, he has distinguished himself as rugby and cricket player, making the school's first teams in both Sports.

# Awon Elewon Tun Ja Ni Ilesha

ILESHA— Awọn ẹlẹwọn tun fi ija peta ninu ọgba wọn ni ọjọ ... ija na pọ to ... ti awọn dẹrẹba ọga wọn ni lati fi ẹrọ isọrọ (telephone) pe awọn ọlọpa wipe ki awọn wa ba awọn dẹrọ ija na.

A gbọ wipe o to wakati meji gbako ti awọn ọlọpa fi ṣe wahala ki awọn to le dẹrọ ija na sugbọn awọn diẹ ti o farapa nibi ija na ni awọn ko lọ si ile awọn alaisan.

Ni aipẹ yi ni rogbodiyan bẹ silẹ ninu ọgba awọn ẹlẹwọn yi kanna ti awọn si pa ọkan ninu wọn. A tiẹ gbọ wipe awọn ọga awọn dẹrẹba nṣe iwadi rogbodiyan na lọwọ nisisiyi

Osi... wa ni awọn a... mojuto ... wa ti tun ... wipe ki awọn se iwadi ... yi, ki awọn si ... awọn dẹrẹba ẹlẹwọn ... ba nhuwa bi ninu ... awọn na.

# Eleti—Ofe D'araba

# Eka Iwe Irohin ELETI-OFE losose



# Loan For Nigerian Cotton Mill Project

**LONDON — Britain's Commonwealth Development Finance Company Limited has agreed to make a secure loan of £400,000 to Norspin Limited of Nigeria for a cotton mill project in Kaduna.**

**The Norspin Company has been formed jointly by the United Africa Company Limited, English Sewing Cotton Company Limited and Dunlop Rubber Company Limited for operating the cotton yarn-spinning mill which will use Nigerian cotton. The mill will supply yarn to the West African Thread Company of Lagos for the manufacture of sewing—thread and knitted fabric for singlets as well as tyre cord and canvas to Dunlop Nigerian Industries tyre factory at Ikeja and will also supply other existing trade channels.**

The Total cost of the project is about £1.6 million and the mill is expected to be in production during 1964.

The Commonwealth Development Finance Company Limited was formed ten years ago by many of Britain's largest industrial and commercial concerns to invest mon y in viable industrial project within the Commonwealth. All the money has been supplied by private investment.

A spokesman for the company told our correspondent in London yesterday, that the CDFC had invested £25 million in the Commonwealth in the last ten year .

Its investments in Nigeria now totalled £2,3?7,000.

## Britain's New High Commissioner In Ghana

LONDON — The Queen has today approved the appointment of Mr. Harold Smedley as British High Commissioner in Ghana, in succession to Sir Geoffrey de Freitas. Mr. Smedley, who is 43, is at present Head of the News Department of the Commonwealth Relations Office. He will take up his new post in January. He has served in the British High Commissioners' Offices in New Zealand, Southern Rhodesia India and was Private Secretary to Lord Swinton and Lord Home (now Sir Alec Douglas-Home, the Prime Minister) when they held office as Commonwealth Secretary. He was educated at Aldenham School and Pembroke College, Cambridge, is married and has four children.

## Ethiopian Finance Minister's London Talks

Lij Yilma Deressa, the Ethiopian Finance Minister, who has just completed a private visit to Britain of several weeks had talks on aid with Mr. Robert Carr, Secretary for Techinical Co-operation, during his stay.

The Minister, who called on a number of banks and business firms to discuss investment in his country, also had talks at the Board of Trade with Mr. E. Du Cann, Minister of State, with the Chancellor of the Exchequer, Mr. Reginald Maudling and with the Joint Minister of State for Foreign Affairs, Mr. Peter Thomas.

## Problems of Growing Populations

KAULA LUMPUR—Problems of growing populations and the need of developing countries for the services of their own overseas trained professional men and women, were two points emerging from technical co-operation discussions at the Commonwealth Parliamentary Association Conference here yesterday, Wednesday.

It was pointed out that qualified professinal men and women often declined to return to their own country after training overseas because they were given greater incentive to stay abroad Consequently professionals from overseas had to be recruited at higher salaries than would would normally have beed paid to their own people.

## Britain's New First Sea Lord



Admiral Sir David Luce, Britain's new First Sea Lord, picture in his Office at the Admiralty in London shortly after taking up his appointment.

Sir David entered there Royal Navy in the submarine service in 1927. After a distinguished career, he pas appointed Commander-in-Chief, Far East Station in 1960, the and became first Commander-in-Chief of British Forces in the Far East in 1962, holding this post until his present appointment.

## Awon Onise Se Aseye Fun Ogbeni Adeshina

EKO — Gbogbo awọn oṣiṣẹ Poo l'Eko ati ni Ebute Metta ni ẹṣẹ wọn pe patapata nibi aṣeyẹ ọku abọ nla kan ti nwọn ṣe fun Ogbẹni Fasasi Adeshina tiṣe alaga alagbaṣe iṣẹ awọn agbe-Poo ti orukọ wọn njẹ Fasasi Adeshina & Sons.

Kansilọ R.A, Balogun ni o ṣe ninu ile nla ti nwọn kọ fun gbigbe awọn oniṣẹ na, Awọn enia pataki pataki ni nwọn si peṣẹ sibẹ.

Ninu ọrọ iyanju ti awọn oṣiṣẹ na pẹlu awọn akọwe wọn fi ki ọga wọn, Ọgbeni Adeshina ku abọ ilu Oyinbo ti o lọ, nwọn ni awọn dupẹ lọwọ Allah ti o mu u pada bọ wa ba awọn, wọn si tun dupẹ lọwọ rẹ fun iwa rere ti ọga na ma nhu si awọn

Gbogbo awọn ti nwọn fi iwe pe sibi aṣeyẹ na ni nwọn fi nkan jijẹ ati mimu tẹlọrun

## Baba Alabiku Ni Ki Won Ma Ka Omo On

Ni Oyingbo l'Ebute-Mẹtta awọn bi iriawo enia lọkuarin lobinrin ti nwọn nsun sinu buka ọja na ni ki nwọn maṣe ka awọn nitoripe ko da awọn loju wipe awọn le ri ere kan jẹ ninu eto eai:-Vika na ju wipe Ijọba ti yio le awọn kuro ni buka ti aw.n nsun lọ.

Gbogbo awọn oṣiṣẹ ti nwọn nṣiṣẹ ni Ikẹja, Apapa ati ibomiran ti nwọn ngbe Mushin, Ọlọrunṣogo, Bariga, Ilupeju ati Suru Lere ni nwọn gbaye nibi iṣẹ lọsan ana lati lọ duro de awọn akọwe akania nile ki nwọn le ri wọn ka

## Awon Egbe Onisegun Sile Iwosan Si Ita Faji

(O bẹrẹ l ju ewe kinni)

O bẹrẹ lori bi alamodi ni ni lati kọ ri dokita ṣe ṣenu iyara ki o ṣe alaye nkan ti o mba a jẹ, ati bi dokita yio ṣe kọwe irufẹ egbogi ti nwọn ni lati lo fun alaisan na.

### Akiyesi

Ni ọse ti mbọ "OLOFINTOTO" Eleti-Ọfẹ yio sọ gbogbo nkan ti o ri ninu ile iwosan awọn onişegun ibilẹ na fun yin.

## Awon Onisowo Ibo Gb'oko Won Lo

(O bẹre lọju ewe kinni)

wipe awọn ko fẹ ki ẹnikan ka awọn rara, nṣe ni nwọn sa wọ inu aginju igbo lọ bamubamu.

Ni irọle ana a si ri irohin kan gba lati Owerri wipe nṣe ni gbogbo awọn agbẹ Ibo duro ni ẹnu ọna abule wọn hahana wipe ki awọn akọwe akania wa ka awọn ti nwọn ko ti raye ka.

GADA FẸ JABỌ

## Ona Ikorodu Tun Baje Leti Itolowo

IKORODU — Awọn ọlọpa ti bẹrẹsi da awọn onimọto nlanla pada ni oju ọna Onigbongbo ni ọna Ikorodu nitori gada Ẹganmoro ti o fẹ jabọ leti abule ti nwọn npe ni Itọlọwọ. Gbogbo awọn mọtọ akepo, bọọsi ati awọn mọto-akero Bọsilẹkaja ni awọn ọlọpa ti nwọn ninu awọn onimọto ti d.pada wipe ki nwọn gba ọna Abẹokuta, ọna ko dara.

Ni ana ọgunlọgọ awọn lebira oniṣẹ oju ọna ni awọn Ijọba ko lọ si ibiti GADA fẹ jabọ na lati ile iṣẹ awọn Olọju ọna ni Ikẹja ti nwọn bẹrẹsi fi okuta rọ gada na lẹgbẹ sibẹsibẹ ko murọ.

THE ANSWER TO
TROPICAL CONDITIONS
★
UNMATCHED
AFTER SALES
SERVICE
★
MERCEDES-BENZ



LEVENTIS MOTORS LTD.
LAGOS (E.B.), IBADAN, KANO, KADUNA, JOS, PORT-HARCOURT, ABA.
Sub-Distributors :—
ARMELS TRANSPORT LTD.
BENIN-CITY . ONITSHA . ABA.

Printed and Published by The Union Printing and Publishing Company, 28, Kosọkọ Street, Lagos
Phone 23370; Editor; (Olotu) Ọla Ọnaṭade, 15, Kosọkọ Street, Lagos, Box 467